# ELETI OFE

'A-NJU-WON KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 928 LAGOS SATURDAY JULY 4 h—JULY 10 1964 KỌBỌ MEJI (2D)


# Eko, Ijebu Ode Ati Ibadan Se Woo Lori Idajo Awolowo

EKO — Igba meii ko gba ara won lode Eko, Ibadan, Ijẹbu-Ode ati awọn ilu miran ni Ipinlẹ Iwọ Orun titi ti o fi de Kaduna ati Enugu ni ọsan ijẹrin Ọjọ'Ru tiṣe ọjọ kinni oṣu yi nigbati Ọlọla Adetokunbọ Ademọla, olori gbogbo awọn adajọ agba ilẹ Nigeria ṣe idajọ ẹjọ kotẹmilọrun ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ tiṣe Olori awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) pe pẹlu owọn mejila yoku. Awon adajọ mẹrin ninu awọn marun ti nwọn ti nwọn gbọ ẹ.ọ na a iwe-ẹjọ Oloye Awolọwọ pẹlu enia mẹsan ya, nwọn ni nwọn jẹbi, ṣugbọn nwọn da awọn en a mẹta silẹ ninu awọn ti nwọn ti ju sẹwọn na.

Awọn mẹta ti nwọn dasilẹ na ni Ayọ Akinsanya, Adeyiga Akinsanya ati Morison Okotie-Yẹsin ṣufọnmu ninu gbogbo awọn adajọ marun na ti o ni Oloye Awoiọwọ ko jẹbi ẹsun kan ni ti on.

gbọn Oloye Awolọwọ pẹlu gbogbo awọn ti a darukọ yi ko wa si kotu rara nigbati adajọ na fi ka iwe idajọ na.

Awọn mẹṣan yoku ti adajọ sọ wipe ki nwọn ma ṣe ẹwọn wọn lọ pẹlu Oloye Awolọwọ ni Latifu Jakandẹ, Michael Omisade, Samuel Otubanjo, Samuel Onitiri, Sebastian Umoren Uzodima Nwabiala, Sunday Ebiotoma, Simeon Oye silẹ ati Gabby Shasosọrẹ.

Ọlọla L ouis Mbanefo olori gbogbo awọn adajọ Ipinlẹ Ila Orun nikan ni o



Oloye ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ

# Tisa Kan Di Obinrin Lojo Idanwo

OWERRI— Laipẹ yi ni a gbọ wipe Tiṣa ile-iwe kan gbe ẹwu obinrin wọ lọ si gbọngan ile-ẹkọ giga kan ti nwọn npe ni St. Catherine's College ni ilu Mbeire ni agbegbe Ọwerri lati lọ ba ọmọ ilewe rẹ kan obinrin ṣe idanwo fun ẹkọ giga.

O pẹ titi lẹhin ti awọn ti nṣe idanwo na ti bẹrẹ iṣẹ, ni ẹniti nṣe alabojuto awọn ti nwọn wa ṣe idanwo n a wa fura si tisa na nibiti o gbe joko si o si pe bọsi ita gbangba lati ba a sọrọ.

Adamọdi ọmọ ile ẹkọ yi kuku ti mọ nkan ti on ṣe, bi o ti jade kuro ninu gbọngan ile-ẹkọ na tan ni o ba fi ere ge bi igala.

Nikẹhin, ọwọ awọn ọlọpa tẹ t i ṣ a na, ẹniti aṣiri orukọ rẹ ṣi farapamọ fun eti igbọ wa, nwọn ti mu lọ si ọgba awọn ọlọpa f u n iwadi ọrọ na nwọn ṣi w a lẹnu ọrọ na lọwọlọwọ.


## LAGOS RACE CLUB

AUGUST MEETING, 1964.

SUNDAYS 2ND, 9TH, 15TH, 23RD AND 30TH AUGUST 1964.

Provisional Programme and Entry Forms can be obtained on application to the Secretary, P.O. Box 51, Lagos or at the Race Course, Lagos.

Note – No Entry fees will be refunded after the draw has been made.

Entries close at noon on Monday 20th July, 1964.

No Cheque will be accepted.

H.H,E. MILLER
Hon. Secretary.

# Dokita Okpara Padanu Lori Ejo Enia Kika

EKO—Ni ọjọ Aje (Monday) ti işe ọjọ kọkandilọgbọn oşu to kọja ni Kotu giga ni ilu Ekọ şe idajọ ẹjọ ti Dokita Okpara, Olotu Ijọba Ipinlẹ Ila Orun pe Ijọbo Apapọşe lori aigungere Ikania ti ọdun to kọja ti adajọ agba si tu ẹjọ na ka nitoripe gẹgẹbi ofin, kotu giga ko ni Ila ẹtọ lati gbọ ẹjọ na, nwọn si paşẹ pe ki ijọba ipinlẹ Iwọ san pọnun mẹ̀ ilelogun ati şile kan (£21 Guineas) fun ijọba Apapọ̀ şe gẹgẹbi owo irin ẹsẹ.

Ninu ẹjọ ti ijọba ẹgbẹ alakukọ ti ipintẹ ila Orun pe si kotu gika, nwọn sọ wipe awọn nfẹ ki kotu paşẹ pe kika enia ni ilu Nigeria, eyiti nwọn şe ni ọdun ti o kọja (1963) ti o fihan pe gbogbo awọn enia ti ngbe ilu Nigeria to ọkẹ mẹtadinlọgbọn o le lẹgbẹrun enia (55,000,000) ko dara, ko si pe nitoripẹ ọna ti Olotu Ijọba Apapọ gbe kika enia na gba ko tọ suna rara,

Agbẹjọro agba fun ijọba Apapọ, Dokita Elias tun tako ẹjọ yi, o si sọrọ lori ipo ẹtọ ti kotu wa nipa gbigbọ ẹjọ na, o si rọ kotu pe ki o tu ẹjọ na ka.

Ninu ọrọ idajọ ti adajọ agba kan, Ọgbẹni Lionel Brett, ọ sọpe ẹniti o pe ẹjọ na ti kuna lati şe alaye bi o ti şe jẹ pe ẹtọ on yio ni ipalara nipa gbigba tabi fifọwọsi kika enia na pe o pe

Kotu giga sọ pe "Bi o ti jẹ pe ọrọ wọnyi jẹ eyiti o wa lati ko eran ran pipin awọn origun ilu si keke e ni, awa gba wipe ẹniti o pe ẹjọ yi ti kuna lati fi ẹtọ rẹ han, eyiti nwọn fi le Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lọwọ gẹgẹbi odidi ilu kan ti o si ni awọn ijoko diẹ ninu ile aşoju ijọba, Ibere ti ọ wa ninu ẹjọ na ko tiẹ sọ idi rẹ ti nwọn fi gbe ẹjọ yi kalẹ, nigbati o jẹ pe awọn gbolohun ti o wa ninu ẹjọ na ni o wa fun lati şe ipalara fun agbra ti ile igbimọ ni, lati yi ẹsẹ kọkanlelogoje (Section 141) ninu iwe ofin imulẹ papa, nitori idi eyi, a pa laşẹ pe kotu giga yi ko ni ẹtọ lati gbọ ẹjọ na."

Ni ipari ọrọ rẹ. adajọ agba ni on şakiyesi pe, yaụọsi awọn ilu ijọba apapọ ẹ miran "Ko jẹ aşa ni ilu Nigeria lati pin awọn adugbo si kekeke lati inu awọn ilu nla gbogbo."

Gẹgẹbi ọro kotu, ofin ti o wa sọpe adugbo kan ko gbọdọ wa fun ju ori ilu kan lọ ni o jẹ eyiti nwọn gbe kalẹ nikan fun anfani ijọba fun ibo didi ninu awọn kotu giga.

Ofin imulẹ-ilu ti ijọba şe işe eyiti ilu kan gbọdọ gbe ẹ ori gẹgẹbi ẹtọ lati ni adugbo kekeke ti nwọn le da silẹ şa kakiri gbogbo ayika rẹ.

Ilu Nigeria ni, ki işe awọn ilu agbegbe rẹ ti nwọn pin si ọna kekere nitori ibo-didi si Ile Aşoju Ijọba, bẹni ki si şe eto ofin imulẹ ilu şişẹ ni nwọn ni ẹtọ si ofin lori agbegbe ilu miran eyiti o faramọ didi ọmọ-ẹgbẹ ti ile Igbimọ.

Ninu ile ajọ,igbimọ (Senate) ni ẹtọ gbe wa nipa awọn ilu nwọn wa ni idabobo. Kotu ko faramọ aroye ti Ijọba Ipinlẹ Ila Orun şe nipa pe awọn owo ti ijọba Apapọşe busi inu awọn ijọba ipinlẹ to ku faramọ gẹgẹbi enia ti pọ to ni ilu kan ju ekeji lọ,

Lori ọrọ akekuru awọn adugbọ ti kotu tun tẹnu mọ julọ, kotu giga ni on gbagbọ pe pipin adugbo si ileto kekeke fun ibo-didi sinu ile ajọ ipade ijọba ti ilu Ila Orun jẹ nkan ti o han gbangba lati lo gẹgẹbi irinşẹ fun ibo-didi si inu ile ajọ igbimọ ti Ijọba Apapọşe,

Ki o to di pe pinpin si ọna meji ti awọn ile igbimọ yi le bọsi, o nilati jẹ pe aşẹ ti ọwọ ijọba ipinlẹ ilu na wa, eyiti o si jẹ pe ile igbimọ aşofin ipinlẹ yio fi ọwọ si.

# Awon Olopa Ye Ile Oloye Awolowo Wo N'Ibadan

IBADAN... Ni owurọ ọjọ Aje (Monday) ti nşe ọjọ kokandin ọgbọ oşu to kọja lọ, wakati mejidinladọta (48 Hrs) si akoko igbati idajọ Oloye Awolọwọ yio jade si eti igbọ gbogbo agbaiye, ẹniti o nşewọn ọdun mẹwa lọwọlọwọ, ni irohin kan wa pe awọn ọlọpa-inu gbe ogun şişe iwadi nla kan ti ile Oloye Awolọwọ ni Oke-Ado ni ilu Ibadan, ti nwọn si tu ibẹ ka boya wọn yio ri ohun ọşẹ kan nibẹ.

Wiwadi na ti awọn agbajọ ọlọpa ati olori wọn ti o jẹ aşiwaju ọgbẹni John Lynn, ti nşe ọga agba fun awọn ọlọpa-inu ni Ikoyi, ni ilu Eko şe jẹ eyiti o nipọn pupọ nwọn si şe titi di owurọ ọjọ Ru ti nşe ọjọ kini oşu keje ọdun yi abẹ abo awọn ọlọpa onibọn ati ponpo.

Irohin na sọpe ohun ti awọn ọlọpa nwa ni awọn ohun ọşẹ bi ibọn ati ọta agba Nitori awọn ibiti nwọn tuka lati wa ohun ọşẹ ni iyẹwu iyawo oloye Awolọwọ wa ati apa kan ninu ile na ninu eyiti igba keji ẹgbẹ ọlọpẹ Alhaji Adegbenro ngbe.

Şugbọn ni oru ọjọ ti nwọn kọkọ şe iwadi na a gbọ pe Alhaji Adegbenro ko si nile bẹni nwọn ba ra şe pe pada si Ibadan lati ju kọkọrọ yara rẹ silẹ fun awọn ọlọpa lati le raye şe işẹ wọn.

A tun gbọ pe awọn ọlọpa tun gbe sunmọmi iwadi na lọ si ile awọn enia meji kan ti nwọn jẹ ọmọ ẹgbẹ ọlọpẹ awọn ni ọgbẹni oloye S. T. Ọrẹdẹin, olupolowo agba, ẹgbẹ ọlọpẹ ati oloye S. O. Lanlẹhin.

Lọ vọlọwọ yi awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ npe ipede gbogbo ọmọ ẹgbẹ wọn kakiri jakejado adugbo kọkan nibiti ẹgbẹ Ọlọpẹ gbe wa

(Wo oju ewe kọjọ )



# Enia Mokanla Fi Ise Igbimo Sile Ni Ilu Ilesha

ILESHA — Ninu ipade igbimọ awọn alakoso eto igbimiko ilu Ilesha kan ti nwọn ṣe ni ọjọ kejidinlọgbọn oṣu kẹfa ọdun yi, awọn enia mọkanla ti ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ tuntun yan gẹgẹbi afunniṣọ si ile Igbimọ Ijọba ibilẹ Ilesha ni nwọn binu fi iṣẹ wọn silẹ ninu ile igbimọ nitoripe nwọn ladi si gẹgẹbi nwọn ti ṣe atojọ awọn ti nwọn yan si igbimọ na, eyiti nwọn ni ko bojumu ti ko si le ri igbadun igbẹkẹle gba lati ọwọ awọn ara ilu Ilesha.

Ipade ifẹṣẹlẹlẹ igbimọ na ti nwọn koko se ṣaju ninu ile ipade igbimọ na ni o o oro nigbati awọn ọmọ ẹgbẹ na kọ lati wasi ipade.

Awọn ọmọ ẹgbẹ igbimọ ti nwọn fiṣẹ igbimọ silẹ ni awọn bi, Alhaji S.A. Eamuyide, E.O. Joshua Fashugba, Ọla Ẹsan, I.O. Awosen. Awọn miran tun ni Ọgbẹni Moses Awe, Gabriel Awe, O. Falude, E Ọdapye ati E. O. Makinde.

Ọpọlọpọ enia ti nwọn wa ninu igbimọ na ti o ni to ọmọ ẹgbẹ merindilọgọta ni nwọn jẹ ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ, ṣugbọn ti o to di pe nwọn tu igbimọ na ka fun atunyan ọmọ ẹgbẹ tuntun, awọn ẹgbẹ Ala u ọ ni nwọn ti nṣe alakoso ẹgbẹ igbimọ na tẹlẹri ni ilu Ileshu.

# Ile Gogoro



Aworan oke yi ni ti ile gogoro ti o wa ni Ilu Oyinbo ninu ile na ile iwe wa ni gbogbo oke kọkan Pẹlu ile onje fun alejo ati onile ni isale pa a-ile na. Pẹlu ile onje fun alejo ati onile ni isale pa ara ni sọbu nla kan ti wọn gbe nta aro ati ohu elo orisirisi.

Ki ole patapata ile na, a mọ yi Kiri, ti o ba wa ni ibẹ ole ri to nkan ti iwọn ibuso meji siwaju ketekete.

Ile yi ni o jẹ ile ti o tobi ju ni ilu Oyinbo ti o si tun ga julọ ni ilu Oyinbo.

O yẹ ki olukuluku gbina ati mọ ile na ni ilu Oyinbo.

# Awon Egbe Kan Fe Fi Idite Ra Ilu Eko

EKO— Ninu ipade kan ti Oloye Fagbẹnro Beyioku, (Aṣiwaju Ẹgbẹ Dẹmọ Nigboro Eko) ṣe pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ na ni Ward B, ni Eletu Iwaṣẹ Public School ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu to kọja lọ, sọ wipe awọn ile iṣẹ kan ti nwọn npe ni Real Estate Company pẹlu ọgọrun ọkẹ pọnun (£2,000,000) ti o si jẹ ti Ibo ndite lati ra gbogbo ilẹ ilu Eko pẹlu owo yi lọwọ, ati wipe ede-ko-yede ti o wa larin ọmọ Yoruba lọwọlọwọ yi ni nwọn fẹ lo gẹgẹbi atipo lati le mu ọtẹ wọn ṣẹ.

Oloye Beyioku fi nye ipade na, lọkunrin ati lobinrin pe, ki iru ọtẹ yi ma le so eso rere jade jẹ fun awọn ọlọtẹ na, afi bi onika luku wọn ba fi kora jọ pọ si abẹ asia ẹgbẹ Dẹmọ, laiṣe bayi iṣoro ni yio si jẹ fun wọn lati le pana ero ọkan awọn Ibo ni ilu Eko Lẹhin eleyi, o tun fi ẹnu kan ajumọṣepọ ẹgbẹ alakukọ ati Ọlọpẹ bi o ti jẹ pe kosi boilewu ki ori, ajọṣe wọn ko le fun wọn ni anfawọn ni kan lati bori ninu idibo ti o mbọ yi, o tun sọ pe ireti awọn ẹgbẹ meji wọnyi yio jasi asan ... ijoko igbimọ ni ilu ariwa,

Siwaju si Oloye Beyioku sọpe gbogbo ijoko igbimọ mejilelogun ti ẹgbẹ ọlọpẹ ji ninu ibo ọdun 1959 na wọn ni adọjọ ọkẹ pọnun (£3,000,000), julọ wayi, on ko bikita bi enia ba npe on ni aworira orilẹ-ede, nitori ẹgbẹ ala ukọ ni o jẹ ijinlẹ ninu iwa bẹ.

Ki o to pari ọrọ rẹ, o si tun sọfun gbogbo ọmọ ẹgbẹ lati ṣakiyesi awọn iṣẹlẹ ati rogbodiyan ti nṣẹle lọwọlọwọ larin ẹgbẹ alakukọ, papa lori ala o ti nwọn gbe ko Oloye T.O.S Benson nitoripe o ngbidanwo lati fi gbolohun kan dasi ọrọ

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

**AKIYESI** Fun anfani enití o mọ itan Oloyinmọmọ ti o fun ọgbọn tabi iran ilu rẹ, ki o kọ ki o ranṣẹ si OLOTU ELETI—ỌFẸ, 28, Kosoko Street, Lagos.

# ELETI-OFE

(A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME

28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 928 SATURDAY July 4th — July 10 1964


## ORO OLOTU

# Ata L'ogun Emi

•

Lati iwọn ni an bi oṣu mẹta sẹhin ni a ti ngburo wipe Minisita alamojuto eto ọkọ oju-omi ati ọkọ-ilẹ, Ọgbẹni Njoku ngbero lati din awọn mọto akẹru ti nwọn npe ni BỌLẸKAJA ti nwọn nko ẹru wọ'lu Eko kn. Irohin na ko dun mọ awọn Obinrin ọlọja rara nitoripe awọn mọto yi ni nwọn fi nṣe BA-MI-KẸRU gbogbo nkan ti ẹnu njẹ, ti nwọn nko wo Eko lati fi ṣe nkan amulo fun onjẹ ti a njẹ lojojumọ.

Nitotọ mọto Bolẹkaja ko ba oju mu ni ode isisiyi, ṣugbọn bi a ba taro ifọn a o họ ara de inu egungun bẹ ena-buruku si ni ọjọ reretirẹ lọtọ, iyẹn ni ti awọn ogunlọgọ Onimọtọ na ti nwọn fẹ daduro.

Ọpọlọpọ awọn ara ilu yi le mà sọ wipe kọ si eyiti o kan awọn lori ọrọ awọn oni mọto bọlẹkaja yi; a fẹ ki gbogbo wa mọ wipe ẹtẹ awo ni ẹtẹ ogbẹri oti pe ọna meji pataki ni awọn onimọto yi fi nṣe iranlọwọ fun awọn ara ilu.

Ọna kinni, awọn oni mọto yi ni nwọn ko ogunlọgọ awọn oṣiṣẹ ti nwọn ko ri mọto wọ wọlu wa ṣe iṣẹ lojujumọ. Ọna keji, awọn oni mọto yi ni o nko nkan onjẹ wọlu, ti nwọn ki jẹki onje wọn pupọ lati ra lọja-eleyi si jẹ pataki fun tọmọde tagba.

Ko yẹ ki a da agunla fun ọrọ awọn oni mọto bọlẹkaja na rara, gbogbo wa ni a mọ wipe ata ni ogun ẹmi. Ti a ko ba fẹ ki epo ati ata di n'kan ti o jẹ wipe awọn Olowo ni yio ma ra wọn, ki a gbarajọ ki o tete lọ bẹ awọn alamojuto eto ọkọ ilẹ wa, ki nwọn jọwọ, bawa ro ọrọ na ṣe, ki wọn fun awọn onimnọto bọlẹkaja ni ọdun meji gbako titi ti aya ilu yio fi balẹ, ti nwọn yio le ṣe eto daradara lati ma fi mọto ko onjẹ wọlu.

Ẹmi ti ko jẹ ata, ẹmi yẹpẹrẹ ni.

# Eleti-Ofe Daraba

# Iwe Si Olotu

# ..ra Sisan Da Hilahilo Sile Ni Ilu Jos

JOS — Ara nla kan ti o san nị ilu Jos laipẹ yị ni o mu hilahilo ba ẹgbẹrun (1000) awọn ọmọ ile iwe kan ti nwọn npe ni St. Fatima Catholic School, nigbati o san pa ọkan nin awọn ọmọ ile-iwe na, ti oruko rr ijẹ Ignatus Udeh ọmọ ọdun mejila ti o si tun pa awọn mẹta miran lara, ti gbogbo awọn toku s fara g a ole ageti.

Iroh,n ti a gbọ g gẹbi nkan yị ti ṣe ṣẹlẹ ni pe, nigbati o di agogo meji a ọsan ọjọ t nkan yị ṣẹlẹ, gbogbo awọn ọmọ ile-iwe yi ni nwọn jade ti nwọn si nṣere lori papa kan ti o jẹ ti ile-iwe wọn ni apapọ pẹlu eyịti o jẹ ti jọba ibilẹ ilu Jos nịnu ọjọ kan tị o nlun, lakoko na ni Udeh pẹlu awọn ẹgbẹ rẹ meje kan fi bọlu gbigba lori tabili ṣire, ṣugbọn lojiji ni ara na san ti o sị pa Udeh, ti awọn mẹta miran ninu awọn ẹgbẹ rẹ si nyị nilẹ fun irora.

Lẹsẹkanna ni nwọn ba gbe awọn mẹtẹta na lọsị ile iwosan nibiti a gbọ pe nwọn nị alafia diẹdiẹ, ṣugbọn Udeh ni ẹniti nwọn gbelọ si ile lakulaku.


**Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, ( Faji Market )

LAGOS NIGERIA.

The House where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

# Adajo Ni K'Obinrin Kan Woleko Apa-pandodo

KAABA— Adajo kotu ibilę kan ni ilu Kabba, ti orukọ rẹ njẹ Oloye Jacob Owonibi, ni ọjọ kẹdọgbọn oşu to kọja, ni o paşẹ pe ki obinrin akọkọ kan lọ fi apapandodo wa ọkọ titun fẹ larin ọgbọn ọjọ ki o ba le ri owo ori rẹ san pada fun ọkọ rẹ ti o pe lẹjọ si kotu kikọsilẹ.

Gẹgẹbi nkan ti a gbọ ni wipe ọkunrin kan ni o ti kọkọ fẹ obinrin na ri ti orukọ rẹ njẹ Rebecca, ki ọkọ rẹ keji, ọgbẹni John Onisuboyin to ai fẹ lẹhin ti o kọ ọkọ rẹ akọkọ silẹ, şugbọn ọkọ keji, Ọgbẹni John sọfun kotu wipe on wa şakiyesi pe Rebecca tun nşẹju si ọkọ rẹ ti akọkọ, o si tun ma nlọsi ile rẹ, nigbakugba ni o si ma nşe ọrọ yi ti on ba bilere ohun ti o nlọ şe nibẹ.

Ọgbẹni John tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe on ri awọn lẹta ifẹ ninu apoti aşọ iyawo on (Rebecca) eyi ti ọkọ akọkọ nko si, ati arişirişi ogun ati ọfọ ti nwọn kọsi inu iwe kekeke ati pe diẹ ninu awọn ọfọ wọnyi wa fun lilo lati le fun obinrin na lagbara lati ni ajulọ lori ọkọ rẹ, papa lati le mu ki obinrin na kọ ọkọ rẹ silẹ.

Nigbati Rebecca ba ri ri ọkọ tuntun fẹ, ẹo tun ma gbọ bi adajọ yio ti pari ọrọ na si laipẹ yi.

## Egungun S'oro Ni Kotu Igbira

OKENE —Ọdun egungun t ọdun yi le pupọ ni ilu awọn Igbira tobẹgẹẹ ti awọn egungun na fi sọrọ wọ inu ikotu kan nibiti adajọ kotu awọn Ọlọpa gbe ndajọ lọwọ, nwọn si na awọn enia inu kotu na ni inakuna ; oju ferese ni awọn miran gbe gba jade nigbati nwọn ngburo atori bi o ti nşeni lọşẹ.

A gbọ wipe kotu na kun bamubamu lọjọ ti awọn egungun yi sare wọ inu ẹ ti nwọn si bẹrẹsi na awọn ti o wa gbẹjọ ni atori. Awọn egungun to jo bata wọ inu kotu na le logun.

Nigbati adajọ ko mọ nkan ti yio şe, nşe ni on

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

# Agbero Inu Bosi Kanwewon Odun Meta

YABA—Larin ọsẹ yi ni a gbọ wipe Adajọ kan ni ile ẹjọ kekere ni Yaba ju ọgbẹni Akanni Babalọla ti ọdun mẹrin lelogun ati igba keji oga agberọ inu bọsi ti igba işẹ ọsanwọn s'ẹwọn ọdun mẹta fun ole ilọnilọwọgba.

Ninu ọjọ kẹrin osu kẹrin ọdun yi Babalọla lọ pọun mẹrin ati şise mẹrin gba mọ Iya Afin Awulatu Aboyarin lọwọ eyiti o fi inu apo ifowopamọ si ni inu oşupa ni ale ọjọ ti a wi yi ni opopo Mc-Cullum ni Ebute-Metta.

Opopo yi ni Iya Abova rin ya si ti Babalọla ati ọrẹ rẹ kan nyo tẹle lẹhin titi nwọn fi ba de ibi kan ti enia ko si ti nwọn fi ni anfani lati şee wọ.

Nigbati nwọn sẹẹ wọ nwọn bilerẹ ohun ti o nwa ni a begbe yẹn ni de de igba yẹn lẹhin ọpọ ọpọ aroye, awọn mejeji wa bilere pe ki o ko gbogbo nkan ti mbẹ lọwọ rẹ silẹ.

Ki o to di pe o fi owo ọwọ rẹ silẹ fun wọn awọn mejeji ti ja gba mọ lọwọ, nwọn wọ kuru nilẹ jina diẹ Babalọla ba fi owo na fun ọrẹ rẹ lati mu doni.

Nigbati awọn ọkunrin meji wọnyi ri pe awọn enia to gbọ wipe obinrin na nsare bọ lati ran lọwọ nwọn fẹsẹ fẹ, Owurọ ọjọ keji ni Awulatu ri Babalola ninu şọbu onigbajamọ (Barber) kan nibiti nwọn nfarungbọn fun.

Gbara ti Awulatu ri si wo ni o tun fere bẹ gbogbo awọn enia ti nwọn wa nitosi ati onigbajamọ papa funrarare rẹ, ọgbẹni Morawo Ajao ba se iranlọwọ lati mu odaran na.

Babalọla şe ni kotu wipe on ko şe ohun ti nwọn fi kan on ati pe awọn fi ọran na dẹ pẹlu ẹ lu on ni, nitori ariyanjiyan kan ti o ti wa arin awọn aburo Awulatu tẹ ẹri.

## Awon Egbe Kan Fe Fi Idite Ra Ilu Eko

(O berẹ loju ewe kẹta)

lori aişododo ti ẹgbẹ alakukọ aşesi awọn ọmọ Yoruba. Nikẹhin o gba ẹgbẹ Demọ iyanju ati awọn agbenilẹsẹ ti nwọn faramọ ẹgbẹ tiwọn yi lati ti sowọpọ lati ja funilọsiwaju ọmọ Yoruba.

YOUR SPECIALIST FOR ALL
BUILDING MATERIALS
BROSSETTE
(NIGERIA) LTD.
WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA
At your service
• STOCK
• SPECIAL ORDERS
• TECHNICAL INFORMATIONS

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin
ELETI -OFE
ti o kun fun irohin aladun losose.

# Obinrin Kan Ja oko ore Re Gba

EKO — Ojo si nkanni gbangba ile-jo kekere kan ni ilu Eko ni ojo Wednesday ti nse ojo kerinlelogun osu to koja nigbati awon obinrin meji kan ti nwon je ore won fija pela lori oko kan.

Nkan ti o fa ija na nipe, nigbati obinrin kan ti oruko re nje Rachel Ajala pe ore re kan ti oruko nje Rachael Ajala pe ore re kan wa si ibi ariya isomoloruko omo re tuntun ti o sese bi, ti o si toka ore re yi si oko re gegebi korikosun on laimope ore on i mbo wa di iyawo oko on.

Oro yi ni Rachael so niwaju adajo kotu kekere kan ni Eko nigbati o nse alaye oro fun adajo bi o ti je pe ore on ti o nje Henrietta fi ona eru gba oko mo on lowo. Telete le, awon olopa ti mu oko Henrietta sejo lori esun ole jija, eni ti oruko re Adeniyi Ajala, sugbon nigbati ise gbe oko Rachael lo si Ibadan mu ore iyawo re yi lowo lo nwon si jo ngbe po bi oko ati aya, Adeniyi fun ore iyawo re loyun. Lojo ti Rachel alatede lo wo oko re ni Ibadan ni awon obinrin meji jo pade ara won lairotele, ninu ile oko yi ase ti o je a'eokoti lohun fun oko ore re, eyit o sokunkun si iyawo. Nigbati Rachel bo sinu apoti eri, o so fun adajo pe Henrietta ti o ja oko a-arede on gba mo on lowo je enit o lowo lowo dje ati pe lehinti on fihan oko on tan gegebi ore korikosun on, ni on to sese wa mo wipe o n e oko mo on lowo.

Oro yi ni o si mu iyapa wa sarin awon mejeji lakoko kan sugbon nwon s pari oro na larin awon ano nis s yi ise ti gbe oko on lo si ilu Ibadan. Lehin ojo die on lo si Ibadan lo ne oko on wo dide ti o ma de ile oko on nsen on ba Henrietta ninu ile.

L ri pe ni an n je iyalenu fun on esekanna ni on bi se wo ie k ni o nwa lodo oko on o si dahun wipe on ti loyun fun Ajala tohun-tenu ija ba besile lori eyi ni Henrietta fi gbeja ko on niwaju kotu iti so kini on tile ni lokan lati se on si dalohun pe oni yi ni yio je opin wiwa re si odo oko mi";

Ija na jo tobe ti gbe awon mejeji lo si ile iwosan fun itoju lori sisan ti nwon fi che n san ara won je Adajo kotu kekere na Iya afin Okunuga ni itoripe obinrin kan je oloro ki ise di si obinrin kan nilati gba fe oko oloko sugbon ko ti pari ejo na fun won o si fi atunegbo ejo na si ojo keje osu keje odun yi eo tun ma gbo gegebi nwon ba ti soro na si lose ti mbo.

---

# eyin onimo-moto

**E sora loju Titi**


CARSON PAINTS AND VANISHES



SOLD AGENTS
IKORODU TRADING COMPANY
20, & 28, Balogun Street Lagos.


THE CARELESS OMOLANKE AND IMPATIENT



# Nigerian Lecturers Tour British Universities

LONDON — Two lecturers from the University of Ibadan and two from the University of Nigeria; Nsukka, have arrived in London to start a tour of British universities and to meet academic figures.

Mr. E.A. Ayandele, 20 a specialist in African history and Anthropology at Ibadan; and Dr. R.K. Udo also a lecturer at Ibadan will spend six weeks in Britain. The two members of the party from Nsukka, Dr 'C E.N. Okpala, a lecturer in the College of Education, and Dr: C. Ebo, lecturer in Political Science, will return to Nigeria two weeks earlier.

During the first two weeks of their stay they will be guest of the British Council and for the remainder of their stay they will tour Britain as guests of the British Government.

As guests of British Council they will visit Oxford University for the day and then will go on to Birmingham, where a programme has been arranged for them by professor Sage of the Institute of African Studies.

The visitors will travel to Edingburgh for 'four days for talks with specials in the subjects they themselves lecture in.

The programme also includes a visit to Canterbury, the famous catheeral city, where they will see the new University of Kent and the historic public school King's School.

On the following day they will start their programme as guests of the Britis Government and will spend most of the time in London, most of it visiting the city's many institutions of higher education.

## Read And Advertise In Eleti-Ofe Weekly News Paper

# Nigerians On Engineering Course In London

LONDON—Following in the footsteps of many compatriots, Mr. O. Ngei from Port Harcourt, and Mr. George Onasanya from Ijebu are studying at the College of Aeronautical and Automobile Engineering in London. The college is the only one in Britain which combines automobile and agricultural engineering in courses in which all theoretical and practical training is done in the college.

There is a great need for engineers in Nigeria and I am sure this need will grow as the country gets more and more motor transport, Mr Onasanya told an LPS correspondent The college's courses are ideal for the needs of a developing country since it aims at training practical engineers rather than academic ones.

Mr. Onasanya has already passed the first part of the examinations of the Institute of Mechanical Engineers, He is also studying garage management at the college since he hopes to enter the motor side of engineering rather than agricultural engineering.

Mr. Ngei, who came to Britain in 1960 .is combining automobile and agricultural engineering and hopes to qualify as a member of both the Institute of the Motor Industry and the Institute of Agricultural Engineers at the end of next year.

Mr. Onasanya and Mr. Ngei intend to work for British firm to gain practical exprience before returning home.

# Catamaran Junk On Trial

One of the rigorous tests applied to the British self-righting catamaran, junk-rigged Rehu Moana, at East India Docks in London, before the set sail recently on a five-man expedition to Arctic seas around Greenland.



# Gbogbo Obinrin Oja Ni Nwon Se D'aro Awolowo

EKO — Gbegede gbina, unjjini bo gbogbo enia agogo ibanuje si nlu ni okan enikeni, lomode isoba lokunrin ati obinrin ni ojo Ojo-Ru ti nse ojo kini osu yi ni ilu Eko ati jake jade ile Naijiria, gbogbo awon obinrin oloja nsokun kikoro bi igbati ofo se se, nigbati kotu giga ju'o ti ijoba Apapo se ni ile Nigeria, ko ejo kotemilorun ti Oloye Awolowo pe siwaju kotu giga yi, ti nwon si so pe o jebi esun ote lati doju ijoba Apapo bo'e, ati pe ki o lo ewon odun m wa re pe gbako pelu awon enia miran.

Ni ile Ila Orun irohin kan wa pe awon obinrin oloja ti nwon nta nkan ninu oja Ogbete ni Enugu ni nwon sare tu gele ori won sonu, awon miran nsokun kikoro, beni opolopo si pale oja won mo, iyanu de ba enikeni nibikibi ni kete ti nwon ti gbo irohin ipa idajo na.

Gbogbo awon enia ti lo si ile awon ti nwon nta onje lati lo jeun ni ilu Enugu ni nwon fi ibanuje ju onje won sile nigbati irohin na de si eti igbo wipe nwon ko ju Awolowo sile ati pe papa julo won ko ti ri iru ibanuje bayi mo ni ilu Enugu ati awon ilu miran ni ile Ila-Orun lehin tabi bi iru igbati Ogbeni Mbonu Ojike ti ku ni odun 1956.

Ni ilu Ibadan gb gbo nkan pa lolo, enia ni nwon si faramo idajo na pelu gbimokai, ti onikaluku s mba se re lo, ile Oloye Awolowo to wa ni Oke-Ado ni Ibadan n nwon tipa, nwon ko si gba ki a'ejo kankan wo ibe awon o'opa enihamora ogun pelu moto won ni nwon si nyi ilu ka, ti nwon si nso ile-ise awon egbe Olope ni Oke-Ado ki awon jandu ka ma le wa soro nibe.

Lori gbogbo isele yi, awon asiju igbimo egbe Olope ni ilu Ibadan nipu ipade kan ti nwon se ni ojo na gaan ni nwon fohun sokan pe awon n gbekele ninu asiwaju awon Oloye Awolowo awon ko si ko lati ba a ku.

Opolopo awon ara oja gbogbo ni igboro Eko ni awon obinrin ko lati taja, ni biba Oloye Awolowo kedun opo opo nu ni nwon dake roro pelu agbegbe kotu na.

Gbo awon omo ile-iwe ti nwon nkig e Awo Awo ni orita Tafawa Balewa ni Eko ni awon olopa fi popo tuka ki eriwo ma ba tun b ilu kan sugbou ko si ipalara kankan. Gbogbo enia lo nrin lojo na bi eyiti ofo se ni kete ti nwon gbo irohin na wipe nwon ko ju Oloye Awolowo sile.

# Awon Marun Ku I Ku Ijagboro Ni Gboko

GBOKO (LEBA MAKURI) A gbo wipe o ti awon enia marun ti nwon ku nibi ija igboro kan to o be sile larin awon ara ilu gbo ko leti Makudi ni ijeta: akowe Ijoba ti ngba woori kan wa ninu awon ti nwon ku na.

Onirohin wa ni awon enia ti nwon farapa ti nwon ru lo si ile awon alaisan Ko niye.

Awon olopa ti ko opolopo awon enia ilu na ti mole pelu ofa obe ati ibon ti nwon ri ko lowo won. A gbo wipe oro awon oselu ni o da ija igboro na sile.

# Awon Olopa Ye Ile Awolowo Wo Ni Ibadan

(O bere loju ewe keji)

Si ile ipade nla won ni ilu Ibadan ey ti won yio se loni ojo Abameta ni Ibadan Ogbeni Bola Ige, eniti o je akowe olupolowo egbe sinu iwe irohin (Publicity Secretary) ti sofun oniwe-irohin owuro kan ni Ibadan ni Ojo Isegun (Tuesday) wipe ninu oro ti ipade egbe na yio so, nwon yio se ipinnu pataki lori awon ohun ti o je mo ti egbe awon.

Ki ogbeni Bola Ige to pari oro re, o ni lehin ti ipade yi ba kase nile tan, ipade awon asoju opomulero egbe awon yio tele.


make it a successful
SEASON
with MERCEDES-BENZ
TRUCKS

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN,
KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA,
PORT-HARCOURT & ABA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos
Phone 23510; Editor, (Olotu) Ola Onatade 15, Kosoko Street, Lagos, P O 467, Lagos.